**Eyi Ti Mbo**

IROHIN IMỌLẸ Ti mbọ yio kun fun aworan to fani mọra, Ajẹgborocagba ni Ilẹ India Itan Ṣebotimọ ati Olotu pẹlu Ọrẹ rẹ ti njẹ yẹyẹnatu, Oni yẹyẹ Eko, ọrọ awọn ọmọ ilẹ Igbomina ati irohin aladun.


# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ .DE, OKUNKUN PARADA.



**Wanted**

Advance Apprentice Compositors

Apply in Person:- POPULAR PRESS 6, Ojo Road, Odu-abọrẹ Mushin.



VOL. V No. 319 MONDAY MARCH 5 — MARCH 11 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


# ADAJỌ GBỌBẸ LỌRUN NINU ILE ẸJỌ

Lati ori apoti Idajo ni Adajo Ijebu-Ode ti de ile Iwosan nigbati o gba obe lorun, o ti pe ti Olaitan Odunsi ni agbo ile aiyegbani ni Imode ti wa ni itimole nitoripe ko san owo ori

Owo ori na ti bi jọ titi, o di pọun mẹtala abọ. Adajọ si da ẹjọ pe lẹhin igbati o ba san owo ori tan ki o san pọun mẹwa gẹgẹbi iya ti o yẹ ki o jẹ fun aisan owo ori ni akoko.

Bi adajọ si ti ṣe idajọ tan, Ọdunsi fi ọwọ si apo, ṣugbọn kaka ki o yọ owo, ọbẹ ni o y ọ, O si de mọ ọrun adajọ. Ṣugbọn awọn ọlọpa ra mu ki o to ju ekeji si, nwọn si gbe adajọ lọ si ile iwosan, Ọdunsi ti pada si iyẹwu rẹ lọdọ ijọba.

## Majekodunmi tajo bo, Ekute ile para mo



EKỌ:- Bi o ti wu, ki ọkọ rẹ okun, ki o si re ọsa, dan dan ni ki o pada wa fi ori fun Elebute wẹrẹ ni Dr. M. A. Majẹkodumi pada wọ ilu eko ninu ọkọ ofurufu lọjọ Friday 2nd oṣu March 1961.

Ọlọla Dokita Majẹkodumi ti o ti fo lọ bi ẹiyẹ si oke okun lati wa awọn olu kọ si ile iwosan University ti ilu Eko Kabọ o, Dọkita tiwa ọwọn, se ọhun ṣe ẹnu re? Ẹ ko ni ṣe ti o.

## Ijoba ju Ademola si Ewon

Owo oṣu Ademọla le ni apo mẹwa lọdun, ọga si ni ni ibi iṣẹ ẹrọ asọrọ magbesi. (N. B. C.)

Ni ọwọ arakunrin kan ti o njẹ Bernett ni Ọ g b ẹ n bi Ademọla Iluyomade ti gbe ẹru ti owo rẹ to pọnun mọkanlelogun.

Ijọba da ẹjọ rẹ ni ọsẹ ti o kọja ni Eko, nwọn ni ki Ọlọla Ademọla lọ gba ẹwa fun oṣu mẹfa pere. Tabi ẹni owo rẹ to apo mẹwa lọdun ki iṣe Ọlọla i?

## Oba Adele fe gbopa lowo Oloye marun

Adele Ọba ilu Eko ti fi siwaju Ijọba pe awọn marun ninu O l o y e on ko tẹ on lọrun mọ, nitorina on fẹ ki nwọn ma ṣe Oloye on mọ. Awọn Oloye na ni Oloye Kosọkọ Asajọn, Ọbanikoro, Onilẹgbalẹ, Olorogun ati Olumẹgbọn. Ijọba ti npe awọn Oloye na ni kọkan lati gbọ ti ẹnu wọn, nitoripe a ki igbọ ẹjọ ẹnikan da.



Oba Adeniji Adele Keji.

Ohun ti o ṣe pataki nipa gbogbo ọrọ na ni pe gbogbo ẹbi awọn Oloye wọn yi ni o wa lẹhin wọn, o si dabi ẹni pe Ọba ni kan ni wọn ṣẹ. (O ni i l ẹ yi jẹ ti La-agba ẹniti nṣe B a b a Ologunkutere ati Ṣokun.)

A si gbọ pe gẹgẹ bi aṣa ti Ijoye kan ba ntẹ awọn ẹbi ti o yan gẹgẹ bi ọ m ọ oye lọrun Ọ b a ko ni aṣẹ lati gba oye lọwọ rẹ, nitoripe Oye Idile ti Oloye yẹn ni. Ni ọsẹ to kọja nigbati Oloye Onilagbalẹ de ọdọ Ijọba, a gbọ wipe o sọ pe ẹjọ ilẹ ni o fa i j a si arin on ati Ọba.

O ni ilẹ kan wa ti o jẹ ajumọni ti ọmọ Ologunkutere eyiti o jẹ Baba kabiyesi, ati ti ọmọ Ṣokun ti o jẹ Baba fun ẹbi Oloye Onilẹgbalẹ (gẹgẹbi o ti jẹ pe ọmọ La-agba ni Ologunkutere ati Ṣokun nṣe.) ṣugbọn Onilẹgbalẹ ni ti awọn ni ẹbi on bere ninu ilẹ na ni Ija ba de.

## Omo odun mokandinlogun ji Omo gbe ni Mushin

Ni Ikeja ni ọsẹ to kọja ni adajọ Ekerutahe dajọ aji ọmọ gbe fun Ṣẹrifatu Olukọga Ọlọpa ni ni ọjọ kẹtadinlogun osu December ni ọdun to kọja, Ṣẹri mura bi ẹniti o fẹ bimọ, o lọ si ile abiye kan ti nwọn npe ni Atonomo ni Mushin ẹniti o wa nibẹ ti o nṣiṣẹ ṣe ayẹwo rẹ o si sọ fun Ṣẹri pe ko loyun ṣugbọn sibẹsibẹ Ṣẹri ko lọ afi igbati o to ri ọmọ kan ji.

## Eku Ipalemo Odun Itunu Awe

# ORO OLOTU

## E je ka ronu

Li ọsẹ tí o kọja, a gbọ pe Ijọba dajọ fun awọn Kansilọ ti ko san owo ori. Ni ọsẹ yi a tun gbọ wipe Ijọba dajọ ẹwọn fun Ọgbẹni kan ti o njẹ Ademọla Iluyọmade, ẹniti owo oṣu rẹ ju ọ g ọ r u n mẹwa pọun lọ lọdun nitoripe o jale

Ni ọsẹ yi kan na ni a tun gbọ pe Ijọ kan yọ Alufa wọn kuro ninu i ṣ ẹ Alufa nitoripe gbeṣe pọ lọrun rẹ ti o njẹ kiri.

### Ẹ TUN JẸ KI A RONU WO

Ọwọ awọn Oṣelu ko mọ, awọn Ọga ibiṣẹ nfẹwọ, Alufa Ijọ ko ṣe gbarale, apẹrẹ tani o ha yẹ ki a wo? Tani yẹ ki a fi ọkan tan? Bẹ ti ẹni to de li a ri, tẹ ni to mbọ a ko mọ, ṣugbọn inu gbogbo Naijiria a d u n jọjọ bi gbogbo ẹnyin o ni iwa buruku ti ẹ nbu enia ku ba fi eyi kọ ọgbọn.

A dupẹ pe ofin I j ọ b a ko ba ẹni kan ṣe ọrẹ; ẹniti ofin ba ri ni ofin ma mu gẹgẹ bi owe Yoruba pe "Ojo ko ba ẹnikan sọrẹ ẹni eji ri ni eji ma npa"

---

WO ỌRỌ YẸYẸNATU ONIYẸYẸ EKO TI O BẸRẸ SI JADE LỌSẸ YI NI OJU EWE KARUN IWE YI.

## Ibon sesi ba Omo ile India kan ni Ikeja

IKẸJA:- A gbọ irohin wipe ọmọkunrin kan ara ilẹ Kamaru, ti o nṣiṣẹ lọdọ Aṣoju ilẹ Kamaru ni ilẹ Egypt ti nwọn npe orukọ rẹ ni Abu-Bagi jẹ ọkan ninu ero ọkọ Ofurufu, ti o balẹ ni ibusọ ọkọ ni Ikẹja, ọkọ na si jẹ ti awọn Larubawa.

Ọkọ Ofurufu na duro lati gba epo, nwọn si ni ki gbogbo awọn ero ọkọ bọ s lẹ, ki wọn lọ gbadun ẹmi wọn ni ile Ọti, olukuluku fi ẹru rẹ silẹ, nwọn lọ fa omi diẹ mu.

Nigbati nwọn pada sinu ọkọ. Ọgbẹni Abu Bagi ṣakiyesi wipe, nwọn ti tu ẹru on wo, ori rẹ gbona, nibiti o gbe nfi wara wara tu ẹru rẹ wo boya nwọn ti ji nikan, o gbagbe wipe Ibọn Rifọfa wa ninu ẹru rẹ, o fi ikanju tu ẹru rẹ wo, o si ṣesi lọ fa oko Ibọn Rifọfa, ni Ibọn ba dahun, o si lọ ba ọmọde kekere kan ti orukọ rẹ njẹ Gulu ara ilẹ India.

Logan nwọn ti gbe Ọmọde na lọ si ile Alaisan ti o mbẹ ni eti odo Alarun (Greek Hospital) Ọrọ na ti di ohun ti awọn Ọlọpa lọwọ sinu rẹ, nwọn si ti da Abu Bagi duro lati ba ṣe ẹjọ.

Ilu Accra ni a gbọ wipe Baba ọmọ na wa kia ti o ti gbọ irohin ohun ti o de si ọmọ rẹ, lo ti ba ọkọ Ofurufu miran de si ilu Eko, o si lọ wo Ọmọ rẹ wo ninu ile Iwosan leti Odo Alarun (Greek Hospital) nibiti nwọn gbe ntọju ọgbẹ rẹ.

FATIMỌ SỌ WIPE:-

## "Augustine ji mi gbe ni"

Ọmọ ọdun mẹwa ni Fatimọ Yisa. Ni Ikẹja lọsẹ to kọja ni gbati o nrọjọ niwaju adajọ o ni lati Kaduna ni Augustine eyi ti ji on gbe wa si Ṣomolu. O ni on nṣe ọmọ ekere rẹ lati igba na, on asi ma so onjẹ fun. Oni o sọ fun on pe ti o ba dagba on yio ra aṣọ fun on, on yio si gbe on ni Iya wo, Ẹjọ na koiti pari

---

## Ilu Rosia yio ma panla fun Ole ati Riba

Lati isiyi lọ ni ilẹ Rọsia ẹnikẹni ti o ba Jale, tabi ti o gba owo ẹhin, tabi to ba Ọlọpa ja tabi di i lọ wọ nigbati o ba nṣi ṣẹ rẹ, pipa ni nwọn yio ma pa.

---

## Awon ara Akure ba ara Eko ja nilu won.

AKURẸ:- A gbọ irohin wipe awọn obirin ara ilu Eko diẹ kan, ko aṣọ lọ ta nigboro Akurẹ, nibiti nwọn gbe nṣatẹ lọwọ ni awọn Obinrin ọja ara Akurẹ bi iwọn Ọdunrun enia fa igi yọ si awọn Obinrin ara Eko na nwọn sile wọn kuro larin Ọja wọn,

Awọn obinrin ara Eko na sa asala lọ ka Ọba Alaiyeluwa Ademuwagun Adeṣida ke ji Deji Akurẹ mọle, agbọ pe awọn obinrin ọja Akurẹ lo titi nwọn fi wọ afin ọba nwọn si kọ lati fi awọn ara Eko na silẹ, ayafi ni gbati awọn ọ l ọ p a Eko de ni nwọn to tu awọn enia na ka.

---

## Adajo ye ejo awon obinrin Oloja si ojomejo oni.



A gbọ irohin w i p e nigbati Ọlọpa fẹ ko ogunlọgọ awọn obinrin ọja lo pamọ si itimọle, awọn Ọlọpa ri pe ko le ṣeṣe lati ko awọn enia na ti gbogbo wọn jẹ Obinrin, nwọn sọ fun wọn pe, awọn mu wọn nitoripe nwọn ko sanwo ori.

Kini awọn Obinrin gbọ bayi si, nwọn tutọ soke, nwọn si fi oju gba wipe, rara o! obinrin kan ko s a n w o ori nilẹ Naijiria ri, nigbati nwọn ni ki awọn obinrin wa sanwo ori nilu Aba, nṣe lo di ogun to di ọtẹ. Nigbati wọn si tun sọ wipe ki obinrin wa sanwo ori ni Abẹokuta, nwọn le Alake gbọnre, a w a na ko kọ ohun ti o le da silẹ a ko ni sanwo ori.

Nigbati Ọlọpa ko nwọn de kotu, o yi ẹsun nwọn pada, o wipe ko nṣe nitoripe nwọn ko san owo o r i ni Ọlọpa ṣe ko wọn, ṣugbọn wọn ṣe ipade oju gbangba laigba i w e aṣẹ Ọba ni on ko wọn fun. Lọya O g u n ni Agbẹjọro w ọ n, Ọgbẹni Anisiobi ni Alatoko wọn, Adajọ yẹ ẹjọ na si ọ j ọ kejila oṣu yi (12th March 1962.) Aworan a w ọ n obinrin ọja na ni a nwo nigbati wọn j o k o si ita Kotu lati gbọ bi wọn tiṣe pari ẹ j ọ wọn.

---

Wanted

TO BUY

Vacant Land any where in Lagos 200 x 200 Call Personally:-

CROWNSON

16, Bamgboṣe- Street Lagos

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Ẹnia lo nle ni debi ola Ẹni

LATI ỌWỌ:— FATAI A. OYERỌGBA

No. 18, Ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

O BẸRẸ LATI ỌSẸ TO KỌJA

Ijoye kan bere lọwọ alejo yi pe, kini ohun ti o wa ni ile ọtun rẹ, Alagbaro yi ni ẹru Ọ b a ni, ile osi rẹ nkọ, Baba yi tun da hun pe ẹru Ijoye ni, Ọba ti o wa ni Itẹ dori kọ, wọn ni ki ni o wa ni ile ọkankan? Alagbaro yi ni ko si nkankan ni ile na. Wọn bi lere ni ẹmẹta, o yege idahun rẹ, ni wọn ba pa Ọba yẹn.

Wọn ba fi Baba Alagbaro yi jẹ Ọba ilu na, gẹgẹ bi a dehun rẹ si ọmọ Ọba ana, o fẹ ọmọ na, Ọlọrun yọnda ọmọ fun Iyawo Ọ b a yi mẹtẹta, gbogbo wọn bi ọkunrin. Ọdun diẹ si ọdun na, Ọba yi Baba Alagbaro ku, ṣe Babalawo kan ko ri ara rẹ loju ọpọn ifa, bẹni Onişegun ko ri ẹbọ iku şe, ti iku ba wọle, ẹniti Jagun ri ni Jagun npa, gbogbo ọmọ kunrin mẹtẹta dagba.

Tani ẹniti o tọ si Oye yi ninu a w ọ n ọmọ Iyawo mẹtẹta, ọmọ Ọ b a akọkọ ni? tabi ọmọ Ọdẹ ti o gba Baba la ni? tabi ọmọ Ọba igbẹhin ni? Mo fi ibere mi yi sọ wọ si gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ aiye lati da hun rẹ.

Lẹkan si, Ẹ ku Ọdun, Ẹ ku Iyedun. Ọlọrun a jẹ ki a şe pupọ rẹ ni aiye. Amin, ẹnikẹniti o ba fẹ da hun rẹ kọwe si F a t a i A. Oyerọgba c/o L. A. Babalọla Akọwe agba Ẹgbẹ I m ọ l ẹ Aiye. 16, Bamgbose Street, Lagos. Olotu mo dupẹ aiye ti ẹ gba mi ninu Iwe yin oloyin momọ, Iwaju ni ọpa ẹbiti nre si, iwaju ni a o ma lọ o, ọkọ ọba ko ni sa yin lẹsẹ o. O digba kan na.


**Are you also Suffering Silently from:-**




TIRED OUT WITH CONSTANT PAIN LIMBS LIKE PIECES OF LEAD BACK-ACHING SWOLLEN JOINTS SHARP SHOOTING PAINS, LUMBAGO, RHEUMATSM - GOUT — ARTHRITIS

Millions of people are suffering under these terrible affliction which constanly impair with the meeling of health THE CAUSE?- EXCESS OF URIC ACID IN THE BLOOD. THE CURE?- UROXAL. The kidneys must be prompted to cleanse from the system the pain-giving heart affecting poisons and this on the evidence of thousands of one-time sufferers restored to normal health condtions by the use of **"UROXAL"** the World reknowned remedy for all Kidney and Bladder affections.

*Price 8/6d Postege 2/6d*

(MADE IN FRANCE)

Stockists:

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**


## Aboderin ninu Igbo Maperan (Apa keji)

LATI ỌWỌ:- ABUDULAHI AWẸLẸNJẸ

No. I, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Itumọ Agbọnrin elere. Ki nṣe wipe agbọnrin ni ẹranko ti o njẹ orukọ yi, Kiniun ni, idi ti a si fi npe bayi ni wipe, ni aiye atijọ bi awọn ẹranko igbọ yi ba fẹ jẹ ọba, nwọn yio yan ẹranko mẹji sita, bi awọn ẹranko wọnyi ba ja tan, eyi ti o ba yege ni yio jẹ Ọ b a na, nigbati akoko Ọba yi to, agbọnrin ni nwọn yan sita pẹlu Kiniun ti wọn si ja titi, nigbati o şe o rẹ agbọnrin o ba lọ fi ẹnu bọ omi, o mu omi titi o si ku, nigbati o ku tan, ni wọn ba fi Kiniun jẹ Ọ b a ti wọn si sọ ni Agbọnrin Alare (Agbọnrin alagbere) ẹranko yi b u r u pupọ depo wipe bi o ba pa aşẹ f u n awọn ẹranko ko si eyiti o gbọdọ gbọnri ninu wọn.

Lẹhin igbati mo ranti gbogbo ọrọ wọnyi ti baba mi wi fun mi, mo fẹ lati lọ mọ ẹranko na, mo ba bọ si agbo, mo si wi bayi pe, ẹ ku iduro, ẹ ku ijoko gbogbo ẹnyin enia, Ọlọrun ko ni jẹki a ma pe nyin si ohun bayi lojojumọ o, lotọ ara ilu yi ni mi, tiko nṣe ọmọ ibi, şugbọn mo ri ami ọrẹ larin yin, ọkan mi si gba lati fi ẹmi mi jiku lati lọ si inu igbo abami yi, mo fẹ ma iti sọrọ delẹ ti gbogbo enia pa atẹwọ fun mi Ọba si pe mi, o ki mi, o bere orukọ mi, emi na wi fun, o ni ki wọn fun mi ni onjẹ, ati aşọ ati yara.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJE

## Awon Asogbo ile Tangayika



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Emiliani M. Temumu ti işe ọkan ninu awọn Aşọgbo nilẹ Tangayika o lọ si ilu Oyinbo lati lọ kọ ilosiwaju ilẹ rẹ fun Royal Forest of Deen. Sa wo bi o ti nfi tayọtayọ gẹ igi ninu igbo, o sọ wipe gẹgẹ bi işẹ na ti wu on to, bi on ba şe idanwo ti on si yege, on yio lọ da işẹ na silẹ ni Tangayika.

POLOWO ỌJA RẸ NINU IWE IROHIN IMỌLẸ

# Yẹyẹnatu!

## ONIYEYE EKO!

Yẹyẹnatu: Olotu, ṣe ẹ ko binu pe nko tete yọju?
Olotu: Nko binu pupọ, ṣugbọn o ya mi lẹnu
Yẹyẹnatu: Bi mo ti nbọ ni oniranu, adaniduro de onigbese kan da mi duro.
Olotu: Tani yẹn kẹ?
Yẹyẹnatu: Ọrẹ nyin ni
Olotu: E wo ninu wọn
Yẹyẹnatu: A ni S u b e r u Ọmọ Jaiye jaiye
Olotu: Kilo wa sọ pe o de
Yẹyẹnatu: Iyawo rẹ ti o fẹ ni ijọsi ti ko ẹru rẹ, o ti lọ, iyẹn ni o wa ba mi sọ.
Olotu: Kini ohun ti o wa ṣe si yẹn kẹ?
Yẹyẹnatu: Ha! ẹ ko mọ pe gbogbo ẹru ti o wa nile Suberu ti Adijatu ni?
Olotu: Lotọ! sọrọ fun mi ki mbula?
Yẹyẹnatu: Nitorina lo ṣe ndamu Suberu pe Adija lọ, Adija lọ.
Olotu: Kilo fa ija wọn papaa?
Yẹyẹnatu: Ṣe ẹ mọ pe Adija njẹ Kofoworọla
Olotu: Nko mọ rara!
Yẹyẹnatu: Ha, o njẹ bẹ. Ṣugbọn o ti sọ pe ẹnikan ko gbọdọ pe on bẹ a fi ọkọ on.
Olotu: Ṣe o ni ki o ma pe on ni Kofo ni?
Yẹyẹnatu: Hẹn o. Ṣugbọn iyẹn na lo tun fa Ija wa yi.
Olotu: Haba! Bawo ni iyẹn ṣe le tun fa ija ẹwẹ! Ṣebi on lo ni ki ọkọ on Suberu ma pe on ni Kofo?
Yẹyẹnatu: Hẹn ṣugbọn o ti ni ko maṣe pe on bẹ mọ nigbati Eko ti npe gbogbo Aṣẹwo ni Kofo.
Olotu: Koforun ni yẹn kẹ, o yatọ si Kofo!
Yẹyẹnatu: Hẹn lotọ ni. Ṣugbọn akoko ti Suberu pe Kofo si, Koforun lo jọ loju awọn enia.
Olotu: Akoko ọdun Keresi ni tabi Ileya?
Yẹyẹnatu: Yago kuro fun mi o jare. A ni gẹgẹ bi o ti ṣe pe e.

Olotu: Hahẹn! bawo ni o ti pe e?
Yẹyẹnatu: O ni ọkunrin kan ti nwa Adija wa ti pẹ. on si sọ fun iyawo on pe ki o ma ṣe jẹ ki o wa mọ, nitori ko yu on, ohun ti o da wọn pọ, ṣugbọn Adija ko gbọ, o ni ọkọ on arv ni, oju ti o ba si ti mọ ni ti ko le sọ pe on ko mọ ni mọ
Olotu: Nigbati Adija ko le ọkunrin na, ṣe iyẹn lo wa dija bayi?

Yẹyẹnatu: Ohun to dija ni pe nigbati ọkunrin na de, Suberu pe Adija o ni "Kofo" ọkọ arọ npe ẹ o.
Olotu: Ha! ha! ha! ha! ki lo sọ be fun? Bo ṣe iwọ na nkọ iru ko ha ni bi ọ
Yẹyẹnatu: Iyẹn na sa lo bi Adija ninu, lo ba da lohun pe, Iya rẹ ni Koforun
Olotu: Ha!
Yẹyẹnatu: Ni ija ba de.
Olotu: H ẹ n! ẹṣe ti o ko jẹki o ma ko ori buruku rẹ lọ?
Yẹyẹnatu: Ha! ko ṣeṣe, o gbag"e pe Suberu ko ni nkankan ẹru Adija lo nlo, onjẹ Adija lo njẹ.
Olotu: O ma ṣe o, aiye ọkunrin, ti obinrin ba mbọ ma ti fọ o. Ki Oluwa ma ṣe jẹ ki obinrin di ọkọ wa. Amin.
Hẹn, ki iwọ na m u r a ṣa lati ba wọn pari ija na, nitori ibukun ni fun awọn onilaja nitori ọmọ Ọlọrun li a o ma pe nwọn.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA

## Awon omo ile Naijiria to lo ko ise Alagbatoju Alaisan



Awọn meji ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ti uwọn lọ kọ iṣẹ olutọju awọn Olokunrun nilu Oyinbo. Ilu ti a gbọ wipe nwọn mọ iṣẹ Iṣegun pupọ ni ilu awọn Ṣ o j a Oniyeri (Scotland) nilu na si ni awọn ọmọ ile Naijiria ti a nwo nwọyi ngbe. Orukọ eyi obinrin njẹ Omidan Ibilọla Ẹbun Oluwa Smith ọmọ ọdun mejilelọgbọn, ti ile wọn wa ni 162, Bamgbose St, Lagos, ati Ọgbẹni F. J. Nwokolo ti o ngbe 45, Odaliki St, Ebutẹ mẹtta, Olukọ wọn lo si kẹta.

## Awon egbe kan fe si Banki titun



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni O l o y e Okotie-Eboh ti awọn ẹgbẹ Alajumọṣe kan towa lati gba iwe aṣẹ lati fi si Banki tuntun kan. Ọkunrin ti o duro, ti o wọ agbada damasi li Alaga awọn ẹgbẹ na, on ni a nwo nigbati Oloye Okotie-Eboh nfun Ọgbẹni S. A. Aboluwọdi ni iwe aṣẹ Banki na, nitori on ni Alaga awọn ẹgbẹ na.

Ma ka Irohin Imole nigba gbogbo

# Eniti o nle wa bo ko tun to eniti a sa di

Lati Ọwọ:- ỌmỌ AIYEGUSI

OLOTU/ Mo juba Ọlọrun adẹda, mo juba awọn alaye, awọn agbagba ati olotu Irohin Imolẹ, Oluwa koni fi arẹ se wa amin. Ẹ jọwọ ẹnyin agba Okeọla ati Iludun nibo ni eyi ti tun wa o, anjẹ ekuru ko tan lawo, awọn kan tun ngbọn ọwọ rẹ sinu awo. Ohun to mu eyi wa ni wipe, laipe yi ni mori iwe kan ti wọn te jede ti wọn pe orukọ iwe na ni Iludun Students Union Magazine' Ni gbati mo bẹrẹ si ka iwe na, mo ka de ibiti wọn ti sọ itan isendale Iluju (Iludun) wọn si fi yemi pe "Asakin" ti o jẹ ọdẹ ni o te ilu na do ati pẹlu wipe Asakin najẹ babagfun "Ade-ifẹ" ni Ika-Oku, on ni o si jẹ Bale kini ni Iludun.

Wọn tun se alaye siwaju pe ilẹ (land) Balẹ na pọ pupọ ti ilẹ na de ilu "IBCDE" ati titi de odo Agbara Okeọla, ati pe awọn ara Iludun ni o ni ilẹ ti awọn Okeọla kọ ile si ni arin Titi Ajaṣẹ ati Titi Iludun

Ẹnyin ara mi, eyi ni awọn ohun ti ko ye mi ninu ọrọ na, ti mo si nfẹ alaye lori re (a) Ara ilu wo ni Asakin ti o tẹ Iludun do (b) Ilu wo ni Asakin na ti wa ni ẹkun mẹsan Oro kio to wa tẹ Iludun do (c) Njẹ to base wipe ọdẹ ni Asakin se wa si Iludun, bawo lo ti wa ri ti a se nka Iludun pẹlu ẹku mẹsan Oro.

Bi iwe itan Magazene na ti dara to awọn (I. S. U.) kose alaye bi ilu wọn ti se ba ẹku mẹsan Oro tan sinu iwe na rara, bẹni o yẹ ki ibatan le mọ ara wọn ni ibatan, ati ọna ti wọn gba fi ba ara wọn tan yala ni idi iya tabi ni idi baba. Ohun patakaki to tun ru ni loju ninu itan wọn na ni wipe ilẹ awọn Iludun ni lati Titi Iludun jasi Titi Ajaṣẹ titi o fi de odo agbara Okeọla. Nitori idi eyi mo nfẹ alaye lati ẹnu ẹnyin baba wa ni ilu Okeọla pe njẹ bẹni ọrọ na ri?. Nitoripe ẹnyin baba wa ko sai ni

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA


## MOGBAYI COUGH MIXTURE

Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣepe lati wo awọn Ikọ orişirişi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde bẹni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, Ikọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arẹ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan miran ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.




Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu, Ẹ ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jẹ 2/6d' arapọ rẹ jẹ 24/-.)

LILO RẸ:-

Ọmọ oşu mẹta—Idaji şibi tii kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oşu mẹta si mejila·- Şibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa.- Şibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba............Şibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

, Balogun Street West, Lagos Nigeria. Phone 22515.

34, Docemu Street, Lagos. Phone 24247.


# Oro nipa igbesi aiye ore

Mo ki gbogbo ẹnyin Olugbọ ọrọ Ọlọrun, Ọlọrun Olodumare yio gbọ ti wa Amin. Egbe ni fun enia nitori nwọn ko gbọ ti Ọlọrun ọrẹ lo sọ enia rere di enia buburu enia buburu koṣe tẹle, gbese ni yio da si Ọlọrun nitorina ẹ tete sun mọ Ouwa yio si gba yin.

Mo ki gbogbo ẹnyin Woli Oluwa koni jẹ kase asẹ jiya, nitoripe kise gbogbo ẹniti o pe mi ni Oluwa Oluwa ni yio wọ ile Ijọba Ọlọrun MATIU 7, ẸSẸ 21

Bo ba se buburu li oju yin lati sin Oluwa ẹyan ẹniti ẹnyin yio ma sin li oni, ati fi han o iwọ ọmọ enia ohun ti odara ati ohun ti Oluwa bere lọwọ rẹ ni ko ṣe ki o ṣe otitọ ki o si fẹ anu ati ki o rin ni irẹlẹ pẹlu Ọlọrun rẹ


WOLI KOGBEREGBE

MIKA 6 ẸSẸ 8

Nitorina gbo gbo ẹnyin Woli ẹjẹ ka bẹru Oluwa nito ripe ọpọlọpọ lo ṣe iṣẹ ti Oluwa ko ran ọ mase jẹki ife owo gbe wa ṣubu, ẹmaṣe wa iyin enia rara, nitoripe ọpọ Woli ni yio ṣegbe nipa ifẹ owo, o ti fẹ owo ju Jesu lọ, nitorina mura emi mbọ kankan ẹre mi pẹlu mi lati san fun olukaluku gẹgẹbi iṣẹ rẹ yio ti ri. IFIHAN 22 Ẹsẹ 12. ọna enia gbogbo ko ju ibi lọ eke, irọ, ẹlẹtan onijibiti lo pọju ni ile niye yi o, mase gbẹkọle enia kan ni ile aiye ti a wa yi, nitoripe osi lo wa nibẹ, ọmọ araiye fẹ ibi ju ire lọ. Ọna alafia ni wọn ko mọ nwọn gbẹkẹle ohun asan ni wọn sọ oke.

Wọn loyun ika wọn mbi iparun, osi ati ibanujẹ leyi jẹ Mase ba ọmọ araiye ṣe ọrẹ kan rara osi lo wa nibẹ Bi aiye ba fẹ ọ la'ọ wọn yio kọ ọ silẹ laro ọla duro de Oluwa yio si gba ọ la.

Nitorina ẹmase gba ọrẹ kan gbọ, ẹ ma si ṣe gbẹkẹle ọmọ enia kan, pa ilẹkun ẹnu rẹ de fun ẹniti osun ni ọkan-aiye rẹ Nitori ọmọ kunrin ṣe aibọwọ fun baba Ọmọbirin dide si iya rẹ aya ọmọ si iyakọ rẹ, Ọta olukaluku ni ara Ile rẹ. Nitorina emi ni ireti si Oluwa emi duro de Ọlọrun Igbala mi, yio si gba mi, Ma yọ mi iwọ ọta mi, bi mo ba ṣubu emi yio dide MIKA 7, ẸSẸ 5.

Alakọri enia lo sope ti Ọlọrun ko si oju yio ti awọn ti ko ba duro de Oluwa, Bi Ọmọ Araiye ko ba gbọ ti Jesu yio pofo ni, osi ati adanu ni enia nitori wọn ko mọ ọrọ Oluwa, Ọmọ araiye fẹran okunkun ju Imọ'ẹ lọ nitori iṣẹ ọwọ wọn buru.


# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, biairọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airişẹşe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nşişẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kona.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ẹjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọkọ bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Şile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunşe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MOLEYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERA

# Aboderin ni ıu Igbo Mape-ran (Apa keji)

LATI OWO:- ABUDULAHI AWELENJE

OBERE LATI OJU EWE KETA

Ti o ni ibusun ki emi na le ri bi fi igegeru mi le lale, nigbati nwon se iwonyi fun mi tan mo bo si iwaju Oba mo dobale gbalaja mo si wi tanu tanu fun Oba bayi, kabiyesi Oba alase ekeji orisa, bi otije isoro fun omi inu agbon ki o danu ni oje isoro fun mi ki nle so bi okan mi ti kun fun ayo to loni, eku owo mi, ohun ti aiye nwa lowo yin Olorun yio jeki eni, ohun ti a si fe lo se laipe yi Olorun yio jeki o dara dandan, a o si gbe ogo ilu yi yo porogodo. Oba na si nwi lekan kan wipe amin, ase, jebe.

Mo gbe ile obe fun bi ojo meta, lojo kerin ope mi, o si ko awon Okunrin merin kan siwaju mi o fi oruko won han mi, okan nje Adera bi oke, Okunrin yi je ogbologbo ode ti o le pa eran ju, eran ti obapo asi ma tobi juti a won yoku lo, oje ologun, oju re mapon kankan ni, ni gbakugba Ekeji Olohun iyo, Okunrin yi ni fere kan bi o ba nfun fere na koda ki esu bayi okan re yio ro wesi ni, Ekete ni Arikutaku Okunrin ti a fi osepe so Okunrin akoni gba ni Okunrin yi, ko si ni iya tabi baba, owo awon eranko lodagba si, osigbo ede eranko

Ekerin ni Onifade, Okunrin na mo ifa pupo, osi ni ogun pupo, oje ijoye kan nilu, osi fe bawa lo.

Nigbati won fi won han mi tan, emi na yan kanngba sita, mo soro bi alujonnu moni, Emi Okunrin niyi, emi Aboderin, baba mi lowo, osi logun, ado ti mbe nile wa lelegbejo, ologun atata si ni mi, gegebi oga ninu irin ajo yi eo gbadun mi, lagbara Olorun mo wi bayitan, oba ba fi ojo lilo wa si ojo kerin atuka onikaluku ba irinke rindo tire lo.

## Nwon da Onigbese Alufa duro

Nigbati alagba, eni owo, olori Alufa S. O. Odutola nsoro ni ipade ododun ti ijo C. M. S. ni Ibadan, o yan leti awon Ijo pe onti da okan ninu awon Alufa duro nitoripe gbese re ti poju.

O ni ki on to se be, on pe ki o so ti enu re, sugbon ko ri ibi yi si pe onigbese gidi ni on nse.

Alagba ni gbese jije ko dara fun eniti o ba wa gegebi Olori Ijo Olorun nitoripe eyi yio ma fun won ni idewo lati ko owo Ijo na.

## Awon Omo Jamani na Omo Naijiria pelu Ese

Ni ose to koja ni Eko ni Naijiria yan a ja - ese mewa ti Hogan Bassy ti ko lati pade awon akan ese ti o wa lati ilu Jamani. Ninu ija yi, Naijiria ko ri okan mu, mewewa o w o Jamani ni o bo si, ko ti le si omi rara. Sugbon awon Omo wa ja bi Okunrin.

## Alufa pari ija Oba meji

O ti pe ti ija ti wa larin Alaiyeluwa Oba Sikiru Adetona, Awujale ti Ijebu-Ode ati Oba Daniel Adetayo Orimolusi ti Ijebu Igbo. Sugbon inu wa dun a si dupe lowo Oluwa pe ija na pari ni ose ti o koja, Alufa S. A. Banjo ni o se Olori awon ti o parapo pari ija na.

A si ni igbagbo pe o ti pari patapata.


## Gbanjo! Gbanjo! O MA NLO GBANJO!!!

A fi eyi kede fun awon onibara wa jake jado Naijiria ati Ghana pe, a o beresi ta awon oja gbanjo wa lati ojo karun osu yi titi di ojo keji osu to mbo. (5/3/62 - 2/4/62) nitorina aye wa fun olukuluku nisisiyi lati ri oja re ra ni opoku oyoku. lehin asiko ti a fi sinu iwe yi, awon oja na yio pada si iye owo won.

Iwe egbogi Ajebidan Agbabietu 25/- tele di 22/-
Iwe Gbedegbeyo Hausa sile meta 3/ tele di 2/-
Iwe Ala ati Iwadi nkan 3/6d di 2/6d
Turari Ajebidan fun eyonu aje ati itaja 10/6d di 7/6d
Idaji Pangolo Turari Ajebidan 8/6d di 5/6d
Idameta 4/6d di 3/-

Fun anfani awon ti o wa ni Ipinle Iwo - Orun Naijiria e wa si odo:-
MANAGER 6, OJO ROAD ODUABORE MUSHIN.

Wo Bus Oshodi ki o sokale ni Bus Stop Mushin nibiti nwon gbe nta Isu tutu. Bere Way Street ti o ba to o de opin, bere 6, Ojo Road, iwo yio si ri ile ise wa.

Fun anfani awon ti o ngbe Eko, lo si odo:-
LATIFU, 16, BAMGBOSE STREET LAGOS.

EGBOGI

# 'CHLORODONT'




Bere fun Egbogi Jamani ti o sese de fun enu rirun tabi 'EHIN ENU ti o ba oyo tabi kika fun ara re,, eyi ni a ma nde ni OMURO EHIN. Kokoro ni o ma ngbe tabi je idi Erki Ehin na, a si ma je ki enu ma run tabi siyon bibaje pelu. Pa kokoro buburu yi run patapata nipa lilo egbogi ti won npe ni CHILORODONT DROPS.

Igo nla:- Silemeje-abo pere 7/6
Igo kekere:- Silemerin pere 4/
OWO OKO Silekan-abo (Postage 1/6d)

BERE FUN

# EGBOGI EKUTE



Ojulowo Egbogi ti opa EKUTE bi monamona laini ewu rara fun enia tabi ohun osin miran ni ile

Silemeji pere ni (2/-) Dosini (£1)
OWO OKO:- Silekan-abo (Postage 1/6d)

Bere Egbogi wonyi ni sobu awon

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

AKIYESI:- Ri daju gbamgba wipe sobu ti won nta lo gbe ranse lora, bi beko awon elomiran yio fi ERU lo ta adamodi tabi orisi omiran fun o, mase gba rara

# FEDERATION OF NIGERIA THIRD DEVELOPMENT LOAN

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966 - to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986 - to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

*W. A. TIBBLES,*
*General Manager.*

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.


## Okunrin kan so kokoro merindiladota modi lai ni apoti kan

ENUGU-: Awọn ọlọpa ki ọkunrin kan mọlẹ, ẹniti awọn enia npe ni Master Key. Nwọn ṣe abere ẹhin wo, kin idi rẹ ti nwọn ṣe npe ọkunrin na ni The Master Key? Nwọn sọ fun awọn ọlọpa pe ko si ilẹkun tabi apoti ti ọkunrin na ko le ṣi. Nigbati awọn ọlọpa gbọ bayi, wọn ranṣẹ pe ọkunrin na ti o njẹ The Master Key nwọn sọ fun pe awọn fẹ yẹ ara rẹ wo, nwọn si ba idi kọkọrọ kan ninu apo rẹ. Nwọn bere pe tita ni kọkọrọ na?.

O si dahun pe, on jogun rẹ lọdọ baba on ni; osọ pe awọn ẹniti kọkọrọ wọn ba sọnu, ọdọ on ni wọn nwa ti on si mba wọn ṣi apoti wọn

Awọn ọlọpa siro gbogbo awọn kọkọrọ na, o jẹ kọkọrọ merindinladọta ati awọn kọkọrọ orisi meji kan ti nwọn kọ orukọ Master Key si lara. Awọn ọlọpa da ọkunrin na duro si itimọle, nwọn Iwadi ọrọ ọkunrin na lọwọ.

## Hu-u haha ! Esurukuru, huu haha!

Mo yọ fun ẹ, mo yọ fara mi hu-u haha. Agbọ lati ẹnu Ọgbeni M. B. Ogundairo, ti iṣẹ Iga Ẹyọ Adimu wipe, wọn o ṣe ẹyọ Ọlayinka Apena ni ọjọ 17th oṣu March 1962

## DURO KO OGBON

Maṣe wa ninu awọn ọmuti; ninu awọn ti nba ẹran-ara awọn tikarawọn jẹ

Maṣe sọrọ li eti asiwere: nitoriti yio gan ọgbọn ọrọ rẹ.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN PE NI:—

# RICHALET

FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buruku ti o ba wa ninu "ẸJE ARA" bi Mọnọmọnọ.
Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TONIKI Ẹjẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimowọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo, Iyọn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yọn tara tabi ti nwọn npota ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawonyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamai, Faranse ati ti awọn Tatanbulu si Itlijẹ. Mọ daju pe bi Ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wonyi le ṣe ọ Lakuregbe, orisirisi Inarun Ojuṣiṣu tabi didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdoki Aya didun Ianpara ekuru laya.

Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amedi Apo ile itọ ẹhin didun tabi Ibaradi riro pẹlu ogbogi Risaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwo yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu nigbakugba.

Bere Egobgi yi ni Ṣọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA


## Enyin Elegungun a bere foji

Anu ṣe ni lati gbọ lẹnu awọn egbẹ Elegungun wipo, akọle oke iwe wa to jade ni ọjọ 22nd oṣu January 1962 wipe Egungun pa Egungun jẹ, eyiti o ba wọn ni orukọ jẹ, Nitori idi eyi, awọn Oniwe Irohin Imọlẹ bẹrẹ fun oji ki oji na si fo wa da. Aṣiṣe ni eyi:

Ẹ jọwọ ẹnyin Ojẹ & Ọmọ Ojẹ Improvement Society, A fi ori ba lẹ o.

Awa ni:-
OLOTU IROHIN IMỌLẸ.

Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Olotu E. A. Adeniji 24, Oliyide Street, Odu Abọrẹ MUSHIN.